# Irinṣẹ́ Àgbègbè Ìpínlẹ̀ New York

Ìtọ́sọ́nà ohun èlò fún àwọn aṣíkiri Ará New York

Oṣù Kinní/Oṣù Kejì Ọdún 2025




New York Immigration Coalition
nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York ṣe àgbékalẹ̀ irinṣẹ́ yìí láti pèsè ohun èlò fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ wa àti àwọn alájọṣepọ̀ wa tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú wọn. Irinṣẹ́ yìí máa ń wà ní ìmúdójúìwọn nígbàgbogbo dá lórí ìyípadà àwọn òfin àti ìlànà.

Imudojuiwọn to kẹhin: 02.24.25

**Atọ́ka àkóónú**


- Ìlera **3**
- Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde **5**
- Àwọn tí wọ́n dé láìpẹ́ yìí àti àwọn tó ń wá ààbò **7**
- Àwọn ohun àmúlò ìdílé **9**
- Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́ **10**
- Ìrólágbára owó **11**
- Ìjọba tiwa-n-tiwa **12**
- Mọ Àwọn ẹ̀tọ́ Rẹ **13**
- Ààbò Àgbègbè **14**
- Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS **15**

# Ìlera



**Ìṣèdúró ìlera**

- Àwọn ènìyàn ìpínlẹ̀ New York lè gba ìdójútòfò ìlera ti ìlú àti ti oko-òwò nípasẹ̀ Àjọ Elétò Ìlera Ìpínlẹ̀ NY.
  - Tí o bá pegedé fún ètò ìdójútòfò ìlera Medicaid, Àkànṣe Ètò Ìdójútòfò Ìlera (Essential Plan), tàbí Ìdójútòfò Ìlera Ọmọdé (Child Health Plus), ìforúkọsílẹ̀ ṣí sílẹ̀ láì ní gbèdéke.
  - Tí o bá gba ìṣúra ìlera ti ìṣòwò, ìforúkọsílẹ̀ tó dá lórí àṣàyàn ẹni yóò bẹ̀rẹ̀ ní 1 Oṣù Kọkànlá, ọdún 2024 tí yóò sì tẹ̀síwájú títí di 15 Oṣù Àkọ́kọ́, ọdún 2025.
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀
  - Gba ìrànlọ́wọ́ ìforúkọsílẹ̀ ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Atọ́nà, fúnra rẹ̀ tàbí lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀. Wá Atọ́nà ní info.nystateofhealth.ny.gov/ipanavigatorsitelocations.
  - Pe Ibùdó Aṣojú Oníbárà Ipò Ìlera NY ní 1-855-355-5777 (TTY: 1-800-662-1220).
  - Lórí ayélujára ní nystateofhealth.ny.gov. Ẹ̀yà Ìtàkurọ̀sọ kan wà lórí wẹ́búsáìtì lákókò àwọn wákàtí ibùdó aṣojú oníbárà láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ fún pípari ìbẹ̀wẹ̀ rẹ.
  - Àwọn olùgbé Ìlú New York: pe 311, tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ "CoveredNYC" sí 877-877, tàbí ṣàbẹ̀wò sí on.nyc.gov/healthinsurance fún ìrànlọ́wọ́ àti àfikún àwọn ohun èlò.
- Wá àlàyé ọlọ́pọ̀ èdè nípa ètò ìlera ní info.nystateofhealth.ny.gov/InformationalMaterials

**Àǹfààní Ìlera tó Fẹjú fún àwọn Olùgba DACA**

- Àwọn olùgba DACA ní báyìí ti kúnjú òṣùwọ̀n fún àǹfààní ìlera lábẹ́ Affordable Care Act (ACA), tí a tún mọ̀ sí Obamacare.
- Àǹfààní ìlera tó fẹjú náà ní Ètò Pàtàkì àti Àwọn Ètò Ìlera tó Kójú Òṣùwọ̀n mìíràn.
  - Tí ọ bá kúnjú ìwọ̀n fún ètò Medicaid, Ètò Abánigbófò fún àwọn àgbàlagbà, tàbí Ètò Ìtọ́jú Ọmọdé, ìforúkọsílẹ̀ wà ní ṣíṣísílẹ̀ fún gbogbo ọdún.
- Láti forúkọsílẹ̀, ṣàbẹ̀wò sí nystateofhealth.ny.gov.

**Ìtànkálẹ̀ Àkànṣe Ètò Ìdójútòfò Ìlera (Essential Plan)**

- Bẹ̀rẹ̀ láti oṣù Kẹ̀ẹrin ọdún 2024, ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ìpínlẹ̀ New York ni wọn ó pegedé fún ètò ìdójútòfò Essential Plan.
  - Ìtànkálẹ̀ ọ̀hún pẹ̀lú àwọn olùgbé ìpínlẹ̀ New York tí owó tí ó ń wọlé fún wọn tó ìdá 250 ìwọn iye owó tó pegedé fún àwọn Ètò Ìrànwọ́ Ìjọba Àpapọ̀ (Federal Poverty Line).
  - Ìtànkálẹ̀ ọ̀hún tún pẹ̀lú àwọn tí wọ́n jẹ àǹfààní Ètò Ìṣíwọ̀lú àwọn Ọmọdé ìyẹn Deffered Action for Childhood Arrival (DACA).
    - Bẹ̀rẹ̀ láti 1 oṣù Kejọ, ọdún 2024, àwọn tí wọ́n jẹ àǹfààní ètò DACA lè gba ètò ìdójútòfò ìlera olówó-pọ́ọ́kú nípasẹ̀ ètò Essential Plan.
    - Bẹ̀rẹ̀ láti 1 oṣù Kọkànlá, ọdún 2024, àwọn tí wọ́n jẹ àǹfààní ètò DACA lè gba ètò ìdójútòfò ìlera olówó-pọ́ọ́kú nípasẹ̀ ètò Qualified Health Plans.
  - Tí o bá ti wà nínú ètò Essential Plan tí o sì wà nínú oyún, o ṣì lè wà nínú ètò tí o wà nínú ẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́, dípò kí wọ́n ṣe àtúnyẹ̀wò fún ọ fún ètò Medicaid.
- Láti mọ̀ síi nípa ètò Essential Plan, kàn sí info.nystateofhealth.ny.gov/EssentialPlan.
- Láti mọ̀ sí i nípa bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀ nínú Ètò Pàtàkì gẹ́gẹ́ bí olùgba DACA, ṣàbẹ̀wò sí on.ny.gov/41sKYcs

**Ètò Medicaid fún àwọn aṣíkiri tí kò ní ìwé-àṣẹ ti ọjọ́-orí 65+ ní Ìpínlẹ̀ New York**

- Bẹ̀rẹ̀ láti Ọjọ́ 1 Oṣù kíní, Ọdún 2024, àwọn aṣíkiri tí kò ní ìwé-ẹ̀rí tí wọ́n ń gbé ní Ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n jẹ́ ọmọ ọdún 65 àti jù bẹ́ẹ̀ lọ, tí wọ́n sì kún ojúwọ̀n fún àwọn ìbéèrè owó àpawọlé kan, yóò ní ẹ̀tọ́ fún Medicaid kíkún (gẹ́gẹ́ bí ìdàkejì Medicaid pàjáwìrì nìkan).
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀
  - Tí o bá ní Medicaid pàjáwìrì lọ́wọ́lọ́wọ́, o lè yípadà sí Medicaid kíkún nípa títẹ̀lé àwọn ìtọ́ni nínú lẹ́tà láti Ipò Ìlera NY.
    - O tún lè yan láti tẹ̀síwájú nípa gbígba Medicaid pàjáwìrì nìkan.
  - Tí ìwọ kò bá ní ìṣèdúró, tí o kò sì ní Ìtọ́jú Pàjáwìrì tẹ́lẹ̀, o gbọ́dọ̀ ṣe ìbẹ̀wẹ̀ rẹ nípasẹ̀ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Àwùjọ Agbègbè rẹ, tàbí Ìṣàkóso Àwọn ohun Èlò Ọmọnìyàn ìlú New York City.
  - Tí ìwọ bá nílò ìrànlọ́wọ́ tàbí ní àwọn ìbéèrè, pe Ipò Ìlera NY ní 1-855-355-5777. Ìrànlọ́wọ́ èdè wà.

# Ìlera



**Àwọn Abẹ́rẹ́ Àjẹsára Aláìléwu tí ó sì Múnádóko ti wà fún COVID-19, Ibà, àti RSV**

- Abẹ́rẹ́ Àjẹsára àrùn COVID-19 ti ọdún 2024-2025 tí a mú d'ójú ìwọn ti wà nílẹ̀.
  - Ìmúdójúìwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID yìí ti bo ọ̀pọ̀lọpọ̀ onírúurú kòkòrò afàìsàn tó ń jà lọ́wọ́lọ́wọ́ tí a ń rí ní Ilẹ̀ New York àti ní U.S.
  - Àjọ tó ń Gbógun ti Ìtànkálẹ̀ Àrùn (CDC) dábàá kí gbogbo ẹni tí ọjọ́-orí rẹ̀ wà ní oṣù 6 àti jù bẹ́ẹ̀ lọ gba ọ̀kan lára àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a mú d'ójú ìwọn.
  - Èyí pẹ̀lú àwọn ènìyàn tí wọ́n ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ÀTI àwọn ènìyàn tí wọ́n ti ní àrùn COVID-19 rí.
  - Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ti ọdún 2024-2025, kàn sí cdc.gov/covid/vaccines
  - Láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 tí a mú d'ójú ìwọn ní ibùdó tó wà ní ìtòsí rẹ, kàn sí vaccines.gov
  - Tí a bá ní àwọn àpẹẹrẹ àrùn COVID-19 tàbí tí o bá wà nínú ewu àti kó àrùn náà, lọ ṣe àyẹ̀wò.
    - Àyẹ̀wò àrùn COVID-19 lè jẹ́ kí o ṣe ìpinnu lórí ohun tí o máa ṣe tí o bá ń ṣe àìsàn, bíi gbígba ìtọ́jú àsìkò láti dènà àìsàn tó lágbára tàbí ìyaraẹnisọ́tọ̀ lójúnà àti mú àdínkù bá ewu títan àìsàn kálẹ̀.
    - Bẹ̀rẹ̀ láti ìparí oṣù Kẹ̀sán ọdún 2024, àwọn ilé'gbéé ní orílẹ̀-èdè U.S. máa lè béèrè fún àwọn àyẹ̀wò àrùn COVID-19 inú ilé ọ̀fẹ́ 4 ní COVIDTests.gov
- Abẹ́rẹ́ àjẹsára Ibà 2024-2025 yi wà lárọ̀ọ́wọ́tó yín báyìí.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára fún ibà tí wọ́n ti ṣe àtúnṣe rẹ̀ máa ń dáàbòbo ẹni lọ́wọ́ onírúurú ibà méta.
  - Ètò CDC dábàá àjẹsára ibà fún gbogbo ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn bẹ̀rẹ̀ láti oṣù 6 àti dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ.
  - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 65 àti dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ, àwọn ènìyàn tó ní pàtó ipò àìlera ọlọ́jọ́ pípẹ́, àwọn ọmọdé àti aròbó, àti àwọn aboyún ni wọ́n wà nínú ewu gíga jù láti ní ìlọ́lù líle láti ibi ìkọlù ibà.
  - Àwọn aráàlú lè tẹ̀lé ìtẹ̀sí ibà ní Ìpínlẹ̀ New York lórí Ẹ̀ka Alépa Ibà nyshc.health.ny.gov/web/nyapd/new-york-state-flu-tracker.
- Abẹ́rẹ́ àjẹsára fún Fáírọ́ọ̀sì Afàìsàn sí Ẹ̀dọ̀fóró àti Òpó-mímí ti wà lárọ̀ọ́wọ́tó.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí lè ṣe ìrànwọ́ ìdènà sí àìlera òpó-mímí ìsàlẹ̀ tí RSV ṣokùnfà.
  - A dábàá abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí fún olúkúlùkù ní ìbámu sí ojú-ọjọ́ wọn àti àwọn ewu ohun okùnfà mìíràn.
    - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 75 àti àwọn tó dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ wà nínú àwọn tí a dábàá kí wọ́n gba àjẹsára.
    - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 60 sí 70 leè bá àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera wọn sọ̀rọ̀ bóyá wọ́n wà nínú ewu gíga ìkọlù àìsàn RSV líle.
    - Àwọn olóyún leè dáàbòbo àwọn ọmọ wọn lọ́wọ́ ìkọlù RSV nípasẹ̀ gbígba àjẹsára alábiyamọ. Àwọn aboyún lè kànsí dókítà ìtọ́jú aboyún/onímọ̀ nípa obìnrin fún àlàyé díẹ̀ si.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára tún wà fún àwọn ìkókó àti ọmọdé tí a mọ̀ sí nirsevamab.
    - lè gba èyí ní Ilé-ìwòsàn lẹ́yìn ìbímọ, àwọn ọmọdé tí wọn kò tíì pé ọmọ oṣù 8 lè gbàá lọ́wọ́ dókítà-ìtọ́jú-ọmọdé.

**Àrùn Mpox**

- Ní oṣù Kẹ̀jọ ọdún 2024, Àjọ Elétò Ìlera Àgbáyé ti kéde àrùn Mpox, tí a mọ̀ tẹ̀lẹ̀ sí monkeypox, gẹ́gẹ́ bíi ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì ajẹmọ́ ìlera ìlú.
- Mpox ma ń sábà tàn ká nípasẹ̀ ìbálòpọ̀, tàbí fífi ara-kan-ara pẹ̀lú ènìyàn tó ní àrùn náà fún ìgbà pípẹ́.
- Àwọn àpẹẹrẹ àrùn Mpox ni ẹ̀sú ara, ìdáranjẹ̀ tàbí oówo ara.
- Àwọn ènìyàn tí wọ́n wà nínú ewu àti kó àrùn náà lè gba abẹ́rẹ́ àjẹsára JYNNEOS.
  - Ọ̀fẹ́ ni abẹ́rẹ́ àjẹsára oníwọ̀n-ìlò méjì ọ̀hún ó sì wà fún àwọn ènìyàn ìpínlẹ̀ New York láì wo ipò ìṣíwọ̀lú, àgbóyé ìbálòpọ̀, tàbí ẹ̀yà ìbí.
  - Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa abẹ́rẹ́ àjẹsára Mpox àti láti rí ibùdó abẹ́rẹ́ àjẹsára, kàn sí cdc.gov/mpox

# Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde



**Àwọn Agbófinró Ìṣíwọ̀lú ní Àwọn Ààyè tí Òfin ní Ìkálọ́wọ́kò sí**

- Ní Oṣù Àkọ́kọ́ Ọdún 2025, ìjọba Trump ti fagilé àwọn àlàkalẹ̀ ọlọ́jọ́ pipẹ́ tó ń darí ICE àti CBP láti yẹra fún gbígbé òfin ìṣíwọ̀lú ró ní àwọn "agbègbè tí wọ́n ní ìkáwọ́kò sí" tàbí "agbègbè tó wà lábẹ́ ìdáàbòbò."
    - Tẹ́lẹ̀, àlàkalẹ̀ yìí pèsè ìdáàbòbò fún àwọn agbègbè bíi àwọn ilé-ẹ̀kọ́, iléeṣẹ́ tó ń pèsè ìtọ́jú ìlera, àti àwọn ààyè ìjọsìn, bákannáà ìsìnkú, ayẹyẹ ìgbéyàwó, àti ìwọ́de, lọ́wọ́ òfin ìṣíwọ̀lú.
    - Nísìsiyìí, ICE àti àwọn iléeṣẹ́ mìíràn ò ní ìkálọ́wọ́kò mọ́ láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ òfin ní àti nítòsí àwọn àyíká yìí.
    - Ìjọba Trump tún ṣàgbéjáde àṣe kan tí yóò gba àwọn gbígbófinró lááyè ní àwọn ilé-ẹjọ́.
- Àwọn aráàlú New York ṣì tún ní ìdáàbòbò díẹ̀ ní àwọn ààyè yìí.
    - Àwọn Àṣe Ìgbìmọ̀ Ìjọba Ìpínlẹ̀ New York 2018 kan fòfin de àwọn agbófinró ìṣíwọ̀lú ní àwọn iléeṣẹ́ ìpínlẹ̀ New York bíi ilé-ẹ̀kọ́ tàbí ilé-ìwòsàn àyàfi tí ICE bá ní ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
    - Àgbékalẹ̀ Òfin Ìdáàbòbò Ilé-ẹjọ́ Wa dáàbòbo àwọn aráàlú New York lọ́wọ́ fífi òfin mú ẹni ní ilé-ẹjọ́ ìpínlẹ̀, ìlú àti ti agbègbè láìsí ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́.
    - ICE àti àwọn aṣojú òfin mìíràn ò leè wọlé sí "àwọn ààyè aládàáni" ibiṣẹ́ kankan láì ní ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́ tàbí ìyọ̀nda oníwun tàbí olùṣàkóso ibiṣẹ́ náà.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nyic.org/2025/02/fact-sheet-trumps-expansion-of-enforcement-in-communities-and-how-sensitive-locations-can-prepare/

**Òfin Laken Riley**

- Wọ́n buwọ́lù Òfin Laken Riley ní 29 Oṣù Kinní, Ọdún 2025. Lábẹ́ òfin tuntun yìí, àwọn olùṣíwọ̀lù kan pàtó tí wọ́n fi ẹ̀sùn ọ̀daràn kàn wọ́n le wà ní àtìmọ́lé ICE láìsí àǹfààní ìbéèrè fún ìtúsílẹ̀ lẹ́yìn sísanwó ìdúró nígbà tí ẹjọ́ wọn wà ní ìdádúró.
    - Àkíyèsí: Kò pọn dandan kí wọ́n dani lẹ́bi ìwà ọ̀daràn kankan kí wọ́n tó lè fi ipá fi ẹni sí ìdádúró dandan.
- Àwọn ọ̀ràn tó lè yọrí sí àtìmọ́lé pẹ̀lú ìfọ́lé, olè jíjà tàbí gbéwiri, ìgbéjà ko agbófinró, àti ìwà ọ̀daràn kankan tó yọrí sí ikú tàbí jàmbá ara tó lágbára sí ẹlòmíràn.
- Tí wọ́n bá mú olùṣíwọ̀lú kankan tí kò ní ìwé ìgbélú fún ikankan nínú àwọn ọ̀ràn tó wà lábẹ́ òfin yìí, wọ́n wà nínú ewu àtìmọ́lé fún gbogbo ìgbà tí wọ́n ó fi máa ṣe ẹjọ́ wọn.
- Òfin Laken Riley ó ní ipa pàtàkì lórí àwọn olùṣíwọ̀lú tí kò ní ìwé-àṣẹ tó wọ U.S. nípasẹ̀ ìrékọjá ibodè lááàrín àwọn èbúté ìwọlé.
- Òfin náà kò kan àwọn:
    - Ènìyàn tó bá ní káàdì aláwọ̀ ewé (Olùgbé ìlú lọ́nà tó tọ òfin)
    - Àwọn ènìyàn tí wọ́n fún ní ipò asásala ní ìta United States tí ó sì fi ipò yìí wọlé
    - Àwọn ènìyàn tó wọlé sí U.S. pẹ̀lú ìwé-àṣẹ ìrìnnà, kódà tí wọ́n bá ti lò ju àkókò tó yẹ lọ.
    - Àwọn ènìyàn tó wà ní "ìyọkúrò ní kíákíá"
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nipnlg.org/sites/default/files/2025-01/2025_NIPNLG-Laken-Riley.pdf

**Àwọn ìlérí fún Cuban, Haitians, Nicaraguans, àti Venezuelans (CHNV)**

- Ní 20 Oṣù Kinní, Ọdún 2025, àgbékalẹ̀ àṣẹ kan sọ pé USCIS yóò dáwọ dúró ìgbàwọlé Fọ́ọ̀mù I-134A, Ìbẹ̀wẹ̀ lórí ayélujára láti jẹ́ Alátìlẹyìn tàbí Ìkéde Àtìlẹ́yìn Lórí Ìnáwó fún àwọn olùbẹ̀wẹ̀ tuntun fún ìtúsílẹ̀ lórí àdéhùn ìwà rere..
- A gba àwọn ènìyàn tó wà ní ipò ìtúsílẹ̀ lórí àdéhùn ìwà rere ní ìyanjú láti bá agbẹjọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú sọ̀rọ̀ nípa àṣàyàn tí wọ́n ní láti bẹ̀wẹ̀ fún àwọn oríṣi ètò ìrànlọ́wọ́ ènìyàn mîìràn.

# Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde

**Ipò Ààbò Ònígbàdíẹ̀ (TPS)**

- Ìjọba orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà lè yan orílẹ̀-èdè àjèjì fún TPS tí àwọn ipò kan, gẹ́gẹ́ bíi ìjà ọmọ ogun tàbí àjálù àdánidá, bá dènà àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yẹn láti padà láìléwu.
- Ní àkókò tí a yàn, àwọn ènìyàn tí wọ́n ń béèrè fún tí wọ́n sì fún wọn ní TPS:
    - Wà ní ìdáàbòbò lọ́wọ́ ìlékúrò nílù.
    - Lè gba ìwé-àṣẹ iṣẹ́ ati nọ́mbà ààbò àwùjọ
    - Lè gba àṣẹ ìrìn-àjò
    - DHS kò lè fi wọ́n sí àtìmọ́lé nítorí ipò ìṣíwá wọn
- TPS jẹ́ ànfàní ònígbàdíẹ̀ tí kò yọrí sí ipò títílái. Síbẹ̀síbẹ̀, àwọn tí wọ́n ní TPS lè béèrè fún ànfàní àwọn aṣíkiri míràn tàbí àwọn ipò àjèjì tí wọ́n ní ẹ̀tọ́ fún.
- Àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n yàn lọ́wọ́lọ́wọ́ fún TPS:
    - Afghanistan, Burma (Myanmar), Cameroon, El Salvador, Ethiopia, Haiti, Honduras, Lebanon, Nepal, Nicaragua, Somalia, Sudan, South Sudan, Syria, Ukraine, Venezuela, Yemen
- Fún àlàyé orílẹ̀-èdè kan pàtó, àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́, àwọn àkókò ìforúkọsílẹ̀, àti àwọn ìmúdójúìwọn tuntun, ṣàyẹ̀wò uscis.gov/TPS.
- Gbogbo àwọn olùbẹ̀wẹ̀ TPS lè bayi lè báyìí fi Fọ́ọ̀mù I-821, Ìbẹ̀wẹ̀ fún Ipò Ààbò ònígbàdíẹ̀, lori ayélujára ní uscis.gov/i-821.
- Wọ́n ti ń ṣe àtúnyẹwò ìpínfúnni ti DHS tí ìjọba Biden ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀. Àtúnyẹwò DHS' sí àwọn ìpínfúnni ti TPS lè yọrí sí fífagi lé òfin ìpínfúnni TPS.
    - Lọ́jọ́ 1 Oṣù Kejì, Ọdún 2025, DHS fagilé ètò TPS fún àwọn ọmọ Orílẹ̀-èdè Venezuela lọ́jọ́ 3 Oṣù Kẹwàá, Ọdún 2023.
        - Àwọn ènìyàn máa pàdánù ipo àti ìwé-àṣẹ ìṣiṣẹ́ wọn lọ́jọ́ 7 Oṣù Kẹrin, Ọdún 2025.
        - Ìfòpin sí yìí ò kan àwọn ọmọ Orílẹ̀-èdè Venezuela tó béèrè fún tí wọ́n sì gba TPS lábẹ́ ìpínfúnni ti ọdún 2021, l'éyì tí yóò wà ní ìmúṣẹ títí di 10 Oṣù Kẹsán, Ọdún 2025.
    - Lọ́jọ́ 20 Oṣù Kejì, Ọdún 2025, DHS fagilé TPS fún àwọn ara Haiti ní ránpẹ́.
        - Àkókò ìmúgbòòrò àti àtúnpín TPS fún àwọn ara Haiti jẹ́ gígé sí Oṣù 18 sí 12, pẹ̀lú déètì tuntun fún òpin rẹ̀ ní 3 Oṣù Kẹjọ, Ọdún 2025. Àkókò ìforúkọsílẹ̀ àkọ́kọ́ fún àwọn olùbẹ̀wẹ̀ tuntun yóò parí ní ọjọ́ 3 Oṣù Kẹjọ, Ọdún 2025.
    - Àwọn ènìyàn tó ní TPS láti Venezuela àti Haiti lè bá agbẹjọ́rò ìṣíwọlú sọ̀rọ̀ láti ri bóyá wọ́n kúnjú ìwọ̀n fún àwọn ètò mìíràn.
    - Àwọn aráàlú le tẹ̀síwájú láti máa ṣàyẹ̀wò àwọn ìpín TPS fún orílẹ̀-èdè wọn àti àkíyèsí ipò wọn.

**Ìgbésẹ̀ ìdádúró fún àwọn èwe tí wọ́n dé (DACA)**

- Lọ́jọ́ 17 Oṣù Kinní, Ọdún 2025, ilé ẹjọ́ Àyíká Karùn-ún fun Ẹjọ́-kòtẹ́milọ́rùn ṣe àgbéjáde ìpinnu tó fọwọ́sí pé ìlànà Ìjọba Biden ti 2022 DACA tó ń pèsè àwọn ànfàání ìwé-àṣẹ iṣẹ́-òòjọ́ fún àwọn olùgbà DACA kò bá òfin mu.
    - Ìpinnu yìí tẹ̀síwájú láti dènà ìjọba láti f'ọwọ́si àwọn ìbẹ̀wẹ̀ DACA tuntun, ṣùgbọ́n àtúnṣe DACA lè tẹ̀síwájú fún àkókò yìí.
- Ní Ọjọ́ 13 Oṣù kẹsàn-án, Ọdún 2023, Ilé Ẹjọ́ Agbègbè Amẹ́ríkà fún Agbègbè Gúúsù Texas dájọ́ lòdì sí DACA, ó ní ètò náà kò bófin mu.
- Ẹjọ́ ń lọ lọ́wọ́, nítorí náà ó ṣe é ṣe kí àwọn àyípadà mìíràn wà sínú ètò náà.
- Ní báyìí, DHS yóò tẹ̀síwájú láti gba àti ṣe ìlànà ìsọdọ̀tun àwọn ìbéèrè DACA (pẹ̀lú ìbéèrè fún ìwé-àṣẹ iṣẹ́ àti ìlọsíwájú ìdásílẹ̀). DHS yóò gbà ṣùgbọ́n kò ní ṣe ìlànà àwọn ìbéèrè DACA àkọ́kọ́.
    - Tí o bá ní DACA lọ́wọ́lọ́wọ́, ipò rẹ ṣì tọ̀nà.
    - Tí DACA rẹ bá parí láàrín oṣù mẹ́fà tó ń bọ̀, tún un ṣe báyìí!
    - Tí o bá fi ìbẹ̀wẹ̀ DACA àkọ́kọ́ sílẹ̀ fún USCIS tí kò sì tí ì wà ní ìtẹ́wọ́gbà, ìbẹ̀wẹ̀ yẹn yóò wà ní ìdádúró. Kì yíò jẹ́ ṣíṣáàyan títí di ìgbà tí wọ́n bá sọ pé ó yá.
- Àwọn ẹni-kọ̀ọ̀kan tí ó ti gba Ìgbésẹ̀ ìdádúró fún àwọn èwe tí wọ́n dé (DACA) lè báyìí fi Fọ́ọ̀mù I-821D (ìbẹ̀wẹ̀ ìsọdọ̀tun DACA) ati I-765 (ìbẹ̀wẹ̀ ìsọdọ̀tun ìwé-àṣẹ iṣẹ́) lórí ayélujára.
    - Ìforúkọsílẹ̀ orí ẹ̀rọ ayélujára wà fún àwọn tí wọ́n ní DACA lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí tí DACA wọn ti parí láàrín ọdún kan séyìn.
    - Fún àlàyé síwájú síi nípa DACA àti bí o ṣe lè ṣe ìsọdọ̀tun ipò DACA rẹ, ṣàbẹ̀wò sí uscis.gov/DACA.

# Àwọn tí wọ́n dé láìpẹ́ yìí àti àwọn tó ń wá ààbò

**Ìmúgbòòrò sí Ìyọkúrò ní Kíákíá Kúrò ní Ilẹ̀ Òkèèrè**

- Lọ́jọ́ 21 Oṣù Kinní, Ọdún 2025, Ẹ̀ka Àkóso Ààbò Ìlú ṣe ìmúgbòòrò èlò ìlànà kan tí a ń pè ní "ìyọkúrò kíákíá."
- Ìyọkúrò kíákíá gba ìjọba láàyè láti tètè lé èèyàn tí wọ́n gbàgbọ́ pé kò ní ìwé-àṣẹ kúrò nílùú, láì farahàn ní wájú olùdájọ́ ìṣíwọ̀lú.
    - Àyàfi kanṣoṣo sí ìyọkúrò kíákíá ni tí èèyàn bá sọ pé òún bẹ̀rù láti padà lọ sí orílẹ̀-èdè rẹ̀ tí ó sì yege ìdánwò ìbẹ̀rù. Èyí le gbàá láyé láti ṣe ìbẹ̀wẹ̀ sí ilé ààbò fún àwọn asásalà.
- Tẹ́lẹ̀, àwọn èèyàn tó wà láààrín máílì 100 sí ibodè nìkan ni ICE àti CBP máa ń lo òfin ìyọkúrò kíákíá fún àti láààrín ọjọ́ 14 tí wọ́n bá dé.
- Nísìsiyìí, àwọn ìjọba ti kéde pé àwon máa lo òfin ìyọkúrò kíákíá lórí ẹnikẹ́ni tí kò bá ní ìwé-àṣẹ nínú ìlú tí kò sì leè fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé wọ́n ti wà ní U.S láìkúrò fún ó kéré jù ọdún méjì ṣáájú ìgbà tí òfin mú wọn.
- Ó yẹ kí ẹni kọ̀ọ̀kan mọ àwọn ẹ̀tọ́ wọn kí wọ́n sì tẹ̀lé ìgbésẹ̀ láti dáàbòbo ara wọn àti àwọn mọ̀lẹ́bí wọn, l'éyì tó pẹ̀lú gbígbé kiri ìwé àkọsílẹ̀ láti fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ ti gbé ìlú ju ọdún méjì lo tí ó bá ṣeéṣe.
- Fún àlàyé díẹ̀ sí, ṣàbẹ̀wò sí nilc.org/resources/know-your-rights-expedited-removal-expansion/



**Ẹ̀tọ́ sí Àwọn òfin Ààyè Ààbò NYC**

- Àwọn ẹbí tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ dé àti àwọn àgbàlagbà tí kò tíì ṣègbéyàwó tí wọ́n wọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà lẹ́yìn ọjọ́ 15 oṣù kẹta, ọdún 2022 lè béèrè fún ààyè ààbò ní ilé ìtura Roosevelt, 45 E 45th St, New York, NY 10017.
    - Ibùdó ibìdésí máa ń wà ní ṣíṣí fún wákàtí 24 lójúmọ́, ọjọ́ 7 ní ọ̀sẹ̀ kan.
    - Àwọn ìwá-ààyè fún lè má jẹ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, nítorí náà àwọn ẹbí gbọ́dọ̀ lọ ní kíákíá láti lọ bèèrè.
    - Fún àlàyé síwájú sí àti ìrànlọ́wọ́ nínú ìbéèrè fún ìwá-ààyè fún ààbò, ṣàbẹ̀wò sí: nyc.gov/site/asylumseekers/resources/additional-resources.page
- Gbígbé ní ààyè ààbò wà ní déédéé àkókò ní ìbámu pẹ̀lú bí o bá jẹ́ ara ẹbí tàbí o jẹ́ àgbàlagbà kanṣoṣo.
    - Àwọn mọ̀lẹ́bí tí wọ́n ní àwọn ọmọ kékeré tí wọ́n wọ ibi ààbò kòní ju ìdúró fún ààbò ọjọ́ 60 lọ. Ní gbogbo ọjọ́ 60, àwọn ẹbí yóò ní láti tún bèèrè fún ìwá-ààyè nínú ètò ààbò.
        - Gbogbo ilé ni àwọn òfin wọ̀nyí wà fún, títí kan àwọn ilé tí Àjọ tó ń rí sí Ọ̀rọ̀ àwọn Aláì-nílé-lórí (DHS) àti àwọn Ibùdó Èsì Pàjáwìrì àti Ìgbé-ayé Gbádùn àwọn Ọmọnìyàn ń darí.
    - Àwọn aṣíkiri tí kò tíì ṣègbéyàwó àti àwọn ìdílé aṣíkiri àgbàlagbà tí wọ́n wọ ibi ààbò kòní ju ìdúró fún ààbò ọjọ́ 60 tàbí 30 lọ dá lórí ẹgbẹ́ ọjọ́ orí wọn.
        - Àwọn aṣíkiri tí ọjọ́ orí wọn wà láàrín ọdún 18 sí 23 kòní ju ìdúró fún ààbò ọjọ́ 60 lọ.
        - Àwọn àgbàlagbà aṣíkiri kan ṣoṣo tí ọjọ́ orí wọn ju ọdún 23 lọ kòní ju ìdúró fún ààbò ọjọ́ 30 lọ.
        - Ìlú náà lè ṣe àfikún ìdúró fún ààbò kọjá ọjọ́ 30 tàbí 60 fún àwọn àgbàlagbà tí kò tíì ṣègbéyàwó lórí ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan
        - Àwọn àgbàlagbà tí wọ́n ní àìlera ni wọn máa fún ní ààyè tí ó gùn ju ọjọ́ 30 tàbí 60 lọ, ní ìbámu pẹ̀lú òfin àpapọ̀, ìpínlẹ̀, àti ìbílẹ̀.
- Àwọn aṣíkiri yóò ní ẹ̀tọ́ láti gba ìmọ̀ràn ní èdè ìbílẹ̀ wọn láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti wá ilé títí láé. Ní kété tí àwọn ènìyàn bá ti dé òpin ìdúró wọn, wọ́n gbọ́dọ̀ ṣe ìgbìyànjú láti wá ibi tí wọ́n máa dúró sí èyí ní ìta ètò ààbò.

# Àwọn tí wọ́n dé láìpẹ́ yìí àti àwọn tó ń wá ààbò



**Ìyípadà Àdírẹ́sì àti Ìyípadà Ibi-ìpàdé**

- Tí o bá ní ẹjọ́ ìwọlé lọ́wọ́lọ́wọ́, o nílò lọ́nà òfin láti ṣe ìmúdójúìwọ̀n àdírẹ́sì rẹ pẹ̀lú ìjọba orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà láàrín ọjọ́ 5 tàbí 10 tí o ti ń lọ, gẹ́gẹ́ bí àjọ tí ó ń bójú tó ẹjọ́ rẹ.
- Nípa yíyípadà àdírẹ́sì rẹ pẹ̀lú àwọn àjọ ti o tọ, ìwọ yóò ríi dájú pé o gba àwọn ìwé pàtàkì nínú méèlì bíi gbígbọ tàbí àwọn ìfitónilétí Ìfọ̀rọ̀ jomítoro.
- Láti yí àdírẹ́sì rẹ padà pẹ̀lú USCIS, fi fọ́ọ̀mù Ìyípadà Àdírẹ́sì sílẹ̀ lórí ẹ̀rọ ayélujára tàbí nípasẹ̀ méèlì.
  - Láti yí àdírẹ́sì rẹ padà lórí ayélujára, ṣẹ̀dá àkọ́ọ́lẹ̀ kan ní myaccount.uscis.gov tàbí fi fọ́ọ̀mù orí ayélujára sílẹ̀ ní uscis.gov/COA
  - Láti yí àdírẹ́sì rẹ padà nípasẹ̀ méèlì, parí Fọ́ọ̀mù AR-11, Káàdì Ìyípadà Àdírẹ́sì Àjèjì, kí o sì fi méèlì ránṣẹ́ sí àdírẹ́sì tí a rí ní Ojú-Ìwé 2 ti fọ́ọ̀mù náà ni uscis.gov/ar-11.
  - Àkíyèsí: O gbọ́dọ̀ fi fọ́ọ̀mù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ sílẹ̀ fún ẹbí kọ̀ọ̀kan tí ó wà nínú ìbéèrè ààbò rẹ.
- Tí o bá wà nínú ìgbẹ́sẹ̀ ìyọkuro, o gbọ́dọ̀ yí àdírẹ́sì rẹ padà pẹ̀lú yálà Ilé Ẹjọ́ Ìwọlé (IC) tàbí Ìgbìmọ̀ Ẹjọ́ Ìwọlé Kòtẹ́milọ́rùn (BIA).
  - Tí kò bá dá ọ lójú nípa àjọ tí ẹjọ́ rẹ wà pẹ̀lú, o lè ṣàyẹ̀wò wẹ́búsáìtì EOIR: acis.eoir.justice.gov.
  - Láti yí àdírẹ́sì rẹ padà lórí ayélujára, fi Fọ́ọ̀mù EOIR-33 / IC tàbí EOIR-33 / BIA sílẹ̀ ní respondentaccess.eoir.justice.gov.
  - Láti yí àdírẹ́sì rẹ padà ní fúnra rẹ tàbí nípasẹ̀ méèlì, tẹ̀lé àwọn ìtọ́nisọ́nà ní ojú-ìwé 2 ti Fọ́ọ̀mù EOIR-33.
  - Àkíyèsí: Ìwọ yóò tún nílò láti fi ẹ̀dá fọ́ọ̀mù ìyípadà àdírẹ́sì rẹ ránṣẹ́ sí DHS OPLA nípa títẹ̀lé àwọn ìtọ́nisọ́nà orí fọ́ọ̀mù náà.
- O lè rí gbogbo àwọn fọ́ọ̀mù ní justice.gov/eoir/eoir-forms.
  - Ìtumọ̀ wà ní èdè Chinese, Haitian Creole, Portuguese, Punjabi, Spanish, àti Russian
- Tí ìwọ kò bá lè lọ sí ibi ìgbẹ́jọ́ rẹ nítorí Ilé Ẹjọ́ Ìwọlé rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́ jìnnà jù àti pé Ilé Ẹjọ́ Ìwọlé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ wà tí ó súnmọ́ àdírẹ́sì tuntun rẹ, o lè fi Ìpinnu sílẹ̀ láti Yí Ibi Ìpàdé Padà.
  - Àkíyèsí: Ìpinnu láti Yí Ibi Ìpàdé Padà ní ó jẹ́ pàtàkì ìbéèrè àti pé ó díjú díẹ̀ ju Fọ́ọ̀mù Ìyípadà Àdírẹ́sì. Wọ́n dá lábàá pé kí o ní agbẹjọ́rò tí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́.
- Fún àlàyé síwájú síi nípa gbígbé, Ìyípadà Àdírẹ́sì, àti Ìyípadà Ibi-ìpàdé, ṣàbẹ̀wò sí:
  - help.asylumadvocacy.org/faqs-moving-traveling

**Àyẹ̀wò-ìwọlé Ìṣíwá**

- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ oríṣiríṣi àwọn ilé-iṣẹ́ aṣíkiri ló wà láàrín ìjọba Amẹ́ríkà. Agbófinró Ìwọlé-jáde àti Ẹ̀só-aṣọ́bodè (ICE) jẹ́ àjọ tí ó mú àwọn òfin ìṣíwá ṣiṣẹ, ati Ètò Àbójútó Ìfarahàn tó lekoko (ISAP) jẹ́ orúkọ fun ètò ICE láti ṣe àbójútó àwọn aṣíkiri kan.
- Àwọn ènìyàn kan ní láti wọlé déédéé pẹ̀lú ICE tàbí ISAP gẹ́gẹ́ bí ara ẹjọ́ wọn. Tí o bá wọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà nípa kíkọjá ààlà tí wọ́n sì tì ọ́ mọ́lé, tàbí tí wọ́n bá tì ọ́ mọ́lé ní ìgbà díẹ̀ lẹ́yìn tí o wọ orílẹ̀-èdè náà, o lè ní àyẹ̀wò-ìwọlé ICE tàbí ISAP.
  - Ti o ba nilo lati wọle, o ṣe pataki lati farahàn sí ibi ìpèsí rẹ. Tí o bá pàdánù ìpèsí rẹ, èyí lè jẹ́ ìrúfin àti pé ó lè ní àbájáde nínú ẹjọ́ ìwọlé rẹ.
  - Ewu wà pé ICE lè fi ọ sí àtìmọ́lé níbi ìpàdé yìí. Èèyàn kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ ṣètò kí wọ́n sì ní ìgbáradì ṣáájú lílọ fún ìpàdé.
- Tí kò bá dá ọ lójú bóyá o ní àyẹ̀wò-ìwọlé pẹ̀lú ICE, o nílò láti ṣètò tàbí ṣe àtúntò àyẹ̀wò-ìwọlé, tàbí kí o ní ìbéèrè nípa àyípadà àdírẹ́sì rẹ, lọ sí ice.gov/check-in.
- Fún àlàyé síwájú síi lórí ìlànà àyẹ̀wò-ìwọlé, ṣàbẹ̀wò sí:
  - help.asylumadvocacy.org/faqs-ice-isap

# Àwọn ohun àmúlò ìdílé



### Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún Ìpínlẹ̀ New York tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀

- Bẹ̀rẹ̀ láti Ọjọ́ 1, Oṣù Kínní, Ọdún 2025, Ìpínlẹ̀ New York máa ṣe àmúwọlé Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀.
- Gbogbo òṣìṣẹ́ ilé-iṣẹ́ aládàáni New York tí ó bá ní oyún yóò lè gba àfikún wákàtí 20 tí a ó sanwó iṣẹ́ rẹ̀, fún Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí àìlera tàbí fún ìtọ́jú inú oyún.
- Ìtọ́jú inú oyún jẹ́ àfikún sí ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí àìlera tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀, kò sì nílò kí a máa jàn án pọ̀. O ti wà nílẹ̀, gbàrà tí òṣìṣẹ́ tí a gbà síṣẹ́ bá ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́.
  - Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún tí a Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀ yàtọ̀ sí Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí Àìlera Ìpínlẹ̀ New York tàbí àwọn àgbékalẹ̀ tàbí ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ mìíràn.
  - Agbanisíṣẹ́ ò lè mú àwọn òṣìṣẹ́ ní dandan láti lo oríṣìí àwọn ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ wọn tán ná kí wọ́n tó lo Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí fún Ìtọ́jú Ìnú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀.
- Àwọn òṣìṣẹ́ lè lo ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ yìí fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ oyún láàrin ọdún kan ṣùgbọ́n kò lè ju wákàtí 20 lọ láàrin ọ̀sẹ̀ 52.
- Gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ àwọn ẹka aládàáni ni lo Ìgbàáyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí fún Ìtọ́jú Ìnú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀ wà fún, láìwo ti iṣẹ́ wọn, ilé-iṣẹ́, tàbí aláàbọ̀ àkókò tàbí aláìsílórí-ipò àfikún àkókò.
- Ìtọ́jú inú oyún ni ìtọ́jú ìṣabiamọ bíi ìṣabiamọ ìkẹ́yinjádedàpọ̀mátọ̀ àti ìtọ́jú ìparí oyún.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí ny.gov/prenatal

### Ìrànlọ́wọ́ owó Empire fún òbí tí ó lọ́mọ

- Gbogbo àwọn ẹbí tí wọ́n ń san owó-orí tí wọ́n ní àwọn ọmọ tí ọjọ́-orí wọn wà lábẹ́ ọdún 17 ni wọ́n pegedé fún àtìlẹ́yìn owó fún àwọn ọmọdé, tí ń ṣe àfikún owó ìpínlẹ̀ New York sí Àtìlẹ́yìn Owó-orí àwọn Ọmọdé ti ìjọba àpapọ̀.
- Tí o bá ní ọmọ tí ó gbẹ́kẹ̀lẹ́ ẹ lábẹ́ ọdun 17, fi owo-ori sílẹ̀, àti gbé ní Ìpínlẹ̀ New York ní kíkún-àkókò (tàbí tí ó ṣègbéyàwó pẹ̀lú ẹnìkan tí ó jẹ́ olùgbé ní kíkún-àkókò) o ní ẹ̀tọ́ láti gba ìrànlọ́wọ́ owó-orí alásanpadà yìí ní àkókò fífiránṣẹ́ àtẹ̀lé.
- Pàápàá jùlọ, Ìrànlọ́wọ́ owó Empire fún òbí tí ó lọ́mọ náà pẹ̀lú àwọn òbí tí wọ́n fi owó orí wọn sílẹ̀ nípa lílo Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Olùsan owó orí Ẹnì kọ̀ọ̀kan (ITIN).
- Fún àlàyé síwájú síi nípa Ìrànwọ́ owó Empire fún òbí tí ó lọ́mọ, ṣàbẹ̀wò sí tax.ny.gov/pit/credits/empire_state_child_credit.htm.

### Ètò ìrànlọ́wọ́ Itọju Ọmọde

- Àwọn Ìdílé ti ní ẹ̀tọ́ báyìí fún ìrànlọ́wọ́ ìtọ́jú ọmọdé tí wọ́n bá ṣe 85% owó tí ìpínlẹ̀ ń wọlé tàbí kéré sí i.
  - Ìdílé kan yóò ní ẹ̀tọ́ tí wọ́n bá ní owó-àpawọlé ọdọọdún tí kò ju:
    - $73,869.56 fún ẹbí ẹlẹ́ni 2
    - $91,250.63 fún ẹbí ẹlẹ́ni 3
    - $108, 631.70 fún ẹbí ẹlẹ́ni 4
    - $126,012.77  fún ẹbí ẹlẹ́ni 5
    - $143,393.84  fún ẹbí ẹlẹ́ni 6
  - Iye owó yóò dín kù sí 1% ti àpapọ̀ owó-àpawọlé ìdílé lókè téńté ààlà òṣì fún àwọn ẹbí tó kópa.
  - Iye ìgbàláàyè sísá jẹ́ 80
- Fún àlàyé síwájú síi àti láti ríi bóyá o lè ní ànfàní láti gba ìtọ́jú ọmọdé ní owó tó kéré tàbí lọ́fẹ̀ ko, ṣàbẹ̀wò sí ocfs.ny.gov/ccap.

# Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́

**Public School System (3K-12)**

- Ìpínlẹ̀ New York ṣe ìdánilójú fún gbogbo ọmọdé, láìka ipò àwọn aṣíkiri sí, ẹ̀tọ́ sí ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ àti ojúlówó, tí ó bẹ̀rẹ̀ ní ilé-ìwé ògoweẹ̀rẹ àti títí tí wọ́n yóò fi gba ìwé-ẹ̀rí ilé-ẹ̀kọ́ gíga dípúlómà, tàbí kí wọ́n dàgbà ní òpin ọdún nínú èyí tí akẹ́kọ̀ọ́ náà yóò di ọmọ ọdún 21.
- Àwọn ìdílé ní ìdánilójú ẹ̀tọ́ sí ìtumọ̀ àti ìtumọ̀-ọ̀rọ̀ ti gbogbo àwọn ìwé-àṣẹ tí ó ní àlàyé pàtàkì nípa ẹ̀kọ́ ọmọdé ní ọ̀nà tí ó bá àkókò mu.
- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè béèrè àti forúkọ sílẹ̀ ní ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba NYS nígbàkúùgbà yípo ọdún, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àṣàyàn lè dínkù ní ìta àkókò ìforúkọsílẹ̀ ìbílẹ̀.
- Àwọn ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba lè má béèrè nípa ipò ìṣíwá àti pé wọn kò ní pín àlàyé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fún ètò ilé-ẹ̀kọ́ ojoojúmọ́ kankan. Àwọn ètò ìgbà èwe ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ pẹ̀lú wákàtí gígùn lè ní àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́ tó dá lórí owó-àpawọlé tàbí ìṣíwá.
- Àlàyé Àwọn ilé-ìwé Ìjọba Ìlú New York
  - Fún àlàyé lórí bí a ṣe lè béèrè fún ìtumọ̀ àti àwọn iṣẹ́ ìtumọ̀ ní Ilé-ìwé Ìjọba NYC, ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/hello tàbí pe 718-935-2013.
  - Fún àlàyé lórí ìlànà ìgbàwọlé, ṣe ìgbàsílẹ̀ "Ìtọ́nisọ́nà Gbígbàwọlé Àwọn ilé-ìwé Ìjọba NYC ti 2023," tí ó wà ní oríṣi èdè èdè 9, ní schools.nyc.gov/admissions.
  - Láti wá àti béèrè wáyé sí Ilé-ìwé Ìjọba NYC, ṣàbẹ̀wò sí myschools.nyc, pe 311, tàbí ṣàbẹ̀wò sí Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé kan. Àwọn agbègbè Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé ni a lè rí ní schools.nyc.gov/fwc
  - Àkókò ìforúkọsílẹ̀ yàtọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú oríṣiríṣi àwọn ìpele akẹ́kọ̀ọ́. Láti rí Àkókò Ìgbàwọlé Fall 2024, ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/enroll.

**Ìrànlọ́wọ́ Owó Kọ́lẹ́ẹ̀jì**

- Gba Ìrànlọ́wọ́ ní UnderstandingFAFSA.org, wẹ́búsáìtì kan tí ó ń pèsè àwọn ìtọ́nisọ́nà àti àwọn ohun èlò fún àwọn ọmọ ilé-ìwé àti àwọn ìdílé tí ń wá owó fún kọ́lẹ́ẹ̀jì.
  - Ìtọ́nisọ́nà Bí-A-Ṣe lè ṣeé FAFSA ọ̀fẹ́ wọn fún Àwọn ọmọ ilé-ìwé gíga wà ní oríṣi èdè méwà
  - Wẹ́búsáìtì náà ti ṣe ìmúdójúìwọ̀n àwọn ojúewé bí-a-ṣe lè ṣeé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí kò ní ìwé-àṣẹ àti àwọn ìdílé aṣíkiri
- Àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó Ìpínlẹ̀ New York
  - Ètò Ìrànlọ́wọ́ Owó Ìkẹ́kọ̀ọ́ (TAP) ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùgbé New York tí ó yẹ láti san owó ìkẹ́kọ̀ọ́ ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí a fọwọ́sí ní NYS.
    - Àmì-ẹ̀yẹ TAP ọdọọdún lè tó $5,665. Nítorí TAP jẹ́ ẹ̀bùn, a kò nílò láti san án padà.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/tap
  - Ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ Excelsior
    - Ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ Excelsior, pẹ̀lú àpapọ̀ àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn, ń jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ sí kọ́lẹ́ẹ̀jì SUNY tàbí CUNY níbi tí wọn kì í sanwó ìkẹ́kọ̀ọ́.
    - Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti àwọn ìdílé tí owó-àpawọlé ọ́dọọdún wọn jẹ́ $125,000 tàbí kéré sí i ní ó ní ẹ̀tọ́ láti béèrè.
    - Ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ Excelsior jẹ́ ṣíṣí sílẹ̀ láti Oṣù Kejìlá, Ọdún 2024 fún Sáà Ètò-Ẹ̀kọ́ Spring 2024-2025.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/excelsior
  - Aṣòfin José Peralta New York State DREAM Act fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn ní àǹfàní sí àwọn ẹ̀bùn àti ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ tí NYS ń ṣàkóso tí ó ń ṣe àtìlẹ́yìn fún iye owó ẹ̀kọ́ gíga wọn.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/dream



# Ìrólágbára owó




**Ìfiránṣẹ́ àkọ́ọ́lẹ̀ owó-orí lórí àpapọ̀ iye tó ń wọlé**

- Àsìkò sísan owó-orí 2025 ti bẹ̀rẹ̀!
- IRS ti bẹ̀rẹ̀ sí ní gba àti gbígbé ìgbésẹ̀ lórí ìfilọ́lẹ̀ owó-orí fún ọdún 2024, tí àkókò fún gbígbà láti parí ni Ọjọ́ Ìṣẹ́gun, 15 Oṣù Kẹrin, Ọdún 2025.
- Ǹjẹ́ ọ nílò ìrànlọ́wọ́ láti kọ ọ̀rọ̀ tó ye sínú àkọsílẹ̀ ìwé owó-orí rẹ?
  - E lè gba ìrànlọ́wọ́ ọ̀fẹ́ láti pinnu iye tí ó yẹ kí owó-orí jẹ́ nípasẹ̀ àwọn olùfarajìn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́-IRS láti ètò Ìrànlọ́wọ́ Olùfarajìn lórí Wíwọlé Owó-ọyà fún Owó-orí (VITA), ètò Olùdámọ̀ràn lórí Owó-orí fún àwọn Arúgbó (TCE), àwọn ètò Ìpèsè Ìrànwọ́ fún Owó-orí Sísan.
    - Àwọn ìpèsè iṣẹ́ yìí wà fún ọ tí owó-ọyà bá jẹ́ $67,000 tàbí kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ, tí ọjọ́-orí rẹ bá jẹ́ 60 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, tàbí tí ọ bá jẹ́ aláàbọ̀ ara tàbí sísọ èdè Gẹ̀ẹ́sì rẹ̀ jẹ́ níwọ̀n ba.
    - Fún àlàyé díẹ̀ sí àti láti ṣàwarí ibi tó wà nítòsí rẹ, ṣàbẹ̀wò sí irs.gov/VITA
  - Ọ sì tún lè kànsí olùfarajìn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́-IRS lórí ayélujára láti kọ ọ̀rọ̀ tó yẹ sínú àkọsílẹ̀ ìwé owó-orí rẹ nípasẹ̀ GetYourRefund.org
    - Ìpèsè yìí wá láìsí ìdíyelé tí owó-ọyà rẹ bá jẹ́ $67,000 tàbí kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ, àti pé ó tún jẹ́ àṣàyàn tó dára fún ọ tí lílo ẹ̀rọ bá jẹ́ ìrọ̀rùn fún ọ
  - Ọ lè ṣe ìgbáradì àti ìfilọ́lẹ̀ owó-orí rẹ fúnra rẹ nípasẹ̀ Ọ̀fẹ́ Ìpẹ́jọ́ IRS irs.gov/freefile
    - Tí owó-ọyà rẹ bá jẹ́ $84,000 tàbí kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ, ó lè wọlé sí ètò ìtọ́sọ́nà ìrànlọ́wọ́ ìfilélẹ̀ àkọsílẹ̀ owó-orí.
- Ṣọ́ra fún ẹ̀tàn! Awon IRS ò ní láíláí fi ọ̀rọ̀ ránṣẹ́, ímeèlì, tàbí kàn sí ọ lórí ẹ̀rọ-alátagbàa láti béèrè fún àwọn àlàyé nípa rẹ tàbí àkọsílẹ̀ owó rẹ.
  - Kẹ́kọ̀ọ́ nípa àwọn ẹ̀tàn owó-orí tó ṣẹlẹ̀ láìpẹ́ àti bí ọ ṣe lè mọ àti ìfisùn ọ̀kan ní irs.gov/alerts

**Fíforúkọsílẹ̀ fún sí fún Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Olùsanwó-orí Olóríjorí**

- Àwọn ITIN wà fún àwọn ènìyàn tí ó jẹ́ dandan fún wọn láti ní nọ́mbà ìdámọ̀ olùsanwó orí ní U.S. ṣùgbọ́n tí wọ́n kò ní, tàbí tí wọ́n kò kúnjú ọ̀ṣùwọ̀n fún, Nọ́mbà Ààbò Àwùjọ (SSN). Níní ITIN yóò fún ọ ní àyè láti ṣètò ìwé ìbéèrè ìdápadà owó-orí àti ẹ̀dínwó owó-orí tí o kúnjú ọ̀ṣùwọ̀n fún.
- Dátà láti Iṣẹ́ Owó-wíwọlé Lábẹ́nú (IRS), pẹ̀lú àlàyé nípa àwọn tó ń fáílì fún owó-orí ITIN, wà lábẹ́ ààbò òfin, tí kò sì yẹ kí wọ́n lòó fún gbígbófinró ìṣíwọ̀lú.
- Jọ̀wọ́ kíyèsí i pé fífi orúkọ sílẹ̀ àti gbígba àṣẹ fún ITIN lè gbà tó bíi oṣù mélòó kan, nítorí náà, ó yẹ kí o forúkọ sílẹ̀ ṣaájú dípò dídúró de àsìkò owó orí sísan.
- Láti mọ̀ síi nípa bí o ṣe lè forúkọ sílẹ̀, irú ẹ̀dínwó owó orí tí o kúnjú ọ̀ṣùwọ̀n fún, àti àwọn àǹfààní mìíràn fún gbígba ITIN, ṣàbẹ̀yò sí taxoutreach.org/tax-filing/itin

**Iye Owó Iṣẹ́ Òṣìṣẹ́ tó Kéré jù Yóò Gòkè Síi ní Ọjọ́ 1, Oṣù Kínní, Ọdún 2025.**

- Bẹ̀rẹ̀ láti Ọjọ́ 1, Osù Kínní, Ọdún 2025, Ìpínlẹ̀ New York yóò gbé iye owó iṣẹ́ òṣìṣẹ́ tó kéré sókè.
  - Ní Ìpínlẹ̀ New York, iye owó iṣẹ́ òṣìṣẹ́ tó kéré jù yóò jẹ́ $15.50.
  - Ní New York City, Long Island, àti Westchester, iye owó iṣẹ́ òṣìṣẹ́ tó kéré jù yóò jẹ́ $16.50.

**Òṣùwọ̀n ìsanwó tuntun tí ó kéré jùlọ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìfi oúnjẹ jíṣẹ́ NYC**

- Tí o bá ṣe ìfijíṣẹ́ ilé oúnjẹ fún ààpù kan ní Ìlú New York, o ní ẹ̀tọ́ láìka ipò ìwọlé rẹ sí.
- Ááàpù rẹ gbọ́dọ̀ san ó kéré jù $19.56 fún wákàtí kan (kìí ṣe pẹ̀lú àwọn ẹ̀bùn) fún àkókò tí o lò ṣiṣẹ́ àwọn ìfijíṣẹ́.
  - Èyí tí ó kéré jù yìí yóò máa pọ̀ sí i ní Ọjọ́ 1 Oṣù Kẹrin lọ́dọọdún.
  - Àwọn ááàpù gbọ́dọ̀ tẹ̀lé àfikún òfin tí ó ń ṣe ìlésí ìsanwó
- Fún àlàyé síwájú sii nípa owó oṣù tó kéré jù àti ẹ̀tọ́ àwọn òṣìṣẹ́, ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/DeliveryApps.
  - Àlàyé wà ní Gẹ̀ẹ́sì, Spanish, Arabic, Bengali, Chinese, Faransé, Haitian Creole, Korean, Polish, Russian, àti Urdu.

# Ìjọba tiwa-n-tiwa

**Ìdìbò-àkọ́kọ́ Alákòóso Ìlú yóò wáyé ní Oṣù Kẹfà Ọdún 2025**

- Ìdìbò-àkọ́kọ́ alákòóso ìlú fún NYC, Albany, àti Buffalo yóò wáyé ní 24th Oṣù Kẹfà Ọdún 2025.
- Láti kópa nínú ìdìbò àkọ́kọ́ yìí ní Ìpínlẹ̀ New York, ọ gbọ́dọ̀ ti wà ní ìforúkọsílẹ̀ sínú ẹgbẹ́ kan tó ń ṣàkóso ìdìbò.
- Ọjọ́ ìkẹyìn láti forúkọsílẹ̀ láti dìbò nínú ìdìbò àkọ́kọ́ yìí, tàbí láti yí àdírẹ́ẹ̀sì rẹ padà, yóò parí ní 14 Oṣù Kẹfà, Ọdún 2025.
- Láti ṣe àtúngbéyẹ́wò ìforúkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi olùdìbò àti ìdarapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ òṣèlú, ṣàbẹ̀wò sí voterlookup.elections.ny.gov
  - Tí ọ bá ní ìbéèrè nípa ipò ìforúkọsílẹ̀ rẹ, kànsí Ìgbìmọ̀ Ìdìbò orílẹ̀-èdè rẹ www.elections.ny.gov/CountyBoards.html
  - Àwọn olùgbé NYC: ṣàbẹ̀wò sí vote.nyc

**Forúkọsílẹ̀ láti dibò**

- Àwọn olùgbé ìpínlẹ̀ New York lè forúkọ sílẹ̀ báyìí láti dìbò lórí ayélujára ní:
  - www.elections.ny.gov/OnlineVoterReg.html
- O lè forúkọ sílẹ̀ láti dìbò tí o bá jẹ́ ọmọ ọdún 16+, ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà àti olùgbé NY fún ó kéré tán ọjọ́ 30 ṣáájú ìdìbò náà.
  - Tí o bá jẹ́ ọmọ ọdún 16 tàbí 17, o lè forúkọ sílẹ̀ tẹ́lẹ̀ láti dìbò ṣùgbọ́n o kò lè dìbò títí di ọmọ ọdún 18.
  - Ìwọ kò lè forúkọ sílẹ̀ láti dìbò tí o bá wà lẹ́wọ̀n fún ìdájọ́ ìwà ọ̀daràn tàbí kí ilé ẹjọ́ dá ọ lẹ́jọ́ pé ọpọlọ rẹ kò ní agbára.
- Ìgbìmọ̀ Ìdìbò NYS: elections.ny.gov/VotingRegister
- Ìgbìmọ̀ Ìdìbò NYC: vote.nyc/page/register-vote
- Forúkọsílẹ̀ lórí ayélujára (tí o bá ní Ìwé-àṣẹ Awakọ̀ NYS, Ìyọ̀nda tàbí Ìdánimọ̀ Ti kii ṣe ti Awakọ̀): voterreg.dmv.ny.gov/MotorVoter
- Béèrè ìwé fọ́ọ̀mù ìforúkọsílẹ̀ kan nípasẹ̀ fóònù (wà ní Gẹ̀ẹ́sì tàbí Spanish): 1-800-FOR-VOTE (1-800-367-8683)
- Kò dá ọ lójú bóyá o forúkọ sílẹ̀ láti dìbò? Ṣàyẹ̀wò ipò ìforúkọsílẹ̀ olùdìbò rẹ ní voterlookup.elections.ny.gov

**Àwọn ẹ̀tọ́ rẹ ní ibùdó ìdìbò**

- Àwọn olùdìbò lè ṣàbẹ̀wò sí ÈYÍKÉYÌÍ nínú àwọn Ibùdó Ìdìbò Ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ní agbègbè tí wọ́n ń gbé, àyàfi ní Ìlú New York, níbi tí wọ́n tí ń yàn àwọn olùdìbò nípasẹ̀ àdírẹ́sì sí ibi ìdìbò ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ KAN.
- Tí o bá gbàgbọ́ pé o ní ẹ̀tọ́ olùdìbò tí o sì ti forúkọ sílẹ̀ ní àsìkò láti dìbò, ṣùgbọ́n a kò lè rí orúkọ rẹ lórí ìwé ìdìbò, o lè béèrè fún ìwé ìdìbò ìgbà ránpẹ́ tàbí ìbúra ẹ̀rí.
- Ìwọ kò nílò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìdánimọ̀ níbi ìdìbò kódà bí o bá jẹ́ olùdìbò fún ìgbà àkọ́kọ́.
- Ìwọ sì lè dìbò tí o bá ń ní ìrírí àìnílé.
- Ní àwọn ipò kan, o sì lè ní ẹ̀tọ́ láti dìbò tí wọ́n bá ti dá ọ lẹ́bi ìwà ọ̀daràn.
- Fún àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́ síi: www.nycvotes.org/how-to-vote/voting-rights
- Àwọn òṣìṣẹ́ kan ní ìpínlẹ̀ New York ní ẹ̀tọ́ láti gba ìsinmi wákàtí méjì tí wọ́n sanwó fún láti lè dìbò. Ṣàyẹ̀wò láti rí bóyá o pegedé: www.elections.ny.gov/NYSBOE/elections/TimeOffToVoteFAQ.pdf

**Láti mọ díẹ̀ sí nípa àwọn ètò ìdìbò àti bí wọ́n ṣe ń ṣiṣẹ́, wo àwọn fọ́nrán wa: nyic.me/civics**



# Mọ Àwọn ẹ̀tọ́ Rẹ



**Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn alájọṣepọ̀ gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa ẹ̀tọ́ wọn nígbàkúùgbà tí wọ́n bá ń ṣe pẹ̀lú Agbófinró Ìwọlé-jáde àti Ẹ̀só-aṣọ́bodè (ICE), Ìpààro Ààlà, tàbí àwọn agbófinró mìíràn.**

**Tí agbófinró ìwọlé-jáde tàbí àwọn agbófinró mìíràn bá dá ọ dúró, rántí:**

- Fara balẹ̀. Má sáré. Má ṣe dènà tàbí dí òṣìṣẹ́ náà lọ́wọ́.
- Má ṣe parọ́ tàbí pèsè àwọn ìwé èké.
- O ní ẹ̀tọ́ lati dakẹ. Ohunkóhun tí o bá sọ ni a lè lò láti fi takò ọ́
- Tí aṣojú kan bá béèrè bóyá wọ́n lè wá ọ tàbí àwọn ohun ìní rẹ, o ní ẹ̀tọ́ láti sọ pé rárá.
    - Síbẹ̀síbẹ̀, o lè má kọjú ìjà gbangba síi.
    - Àwọn ọlọ́pàá lè tẹ́ aṣọ rẹ mọ́lẹ̀ tí wọ́n bá fura sí ohun ìjà.
- Tí o kò bá jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí aṣojú agbófinró ìwọlé-jáde sì béèrè fún ìwé ìwọlé rẹ, o gbọ́dọ̀ fi hàn wọ́n tí o bá ní wọn pẹ̀lú rẹ.
- Tí wọ́n bá dá ọ dúró, tí wọ́n tì ọ́ mọ́lé, tàbí kí àwọn agbófinró ṣe inúnibíni sí ọ, gbìyànjú láti gba orúkọ aṣojú náà, nọ́mbà, àti àlàyé ìdánimọ̀ mìíràn.
- Ìwọ tàbí ẹlòmíràn ní agbègbè náà lè ya fídíò tàbí ìgbàsílẹ̀ ohùn ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró. O tún lè kọ ohun tó ṣẹlẹ̀ sílẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá kúrò.
- Kò bófin mu fún àwọn agbófinró láti ṣe ìdádúró èyíkéyìí, ìwádìí, ìtìmọ́lé, tàbí ìkọlù tí ó dá lórí ẹ̀yà rẹ, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ẹ̀sìn, ìbálòpọ̀, tàbí ẹ̀yà.

**O lè ṣe ìjábọ̀ ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn aṣojú ìjọba àpapọ̀ sí Immigrant Defense Project (IDP).**

**IDP tún pèsè àlàyé òfin àti ìtọ́kasí fún àwọn aṣíkiri tí wọ́n ti mú, tí wọ́n ti gba tíkẹ́ẹ̀tì, tàbí tí wọ́n dá lẹ́bi ìwà ọ̀daràn. Pe 212-725-6422 tàbí ímeèlì info@immdefense.org**

**Àwọn ààyè Ìdákọ́ńkọ́**

- Ilé rẹ àti àwọn "ààyè ìdákọ́ńkọ́" mìíràn (gẹ́gẹ́ bí àwọn agbègbè òṣìṣẹ́ nìkan ní ibi iṣẹ́) gbé ààbò pàtàkì tí àwọn ààyè gbogbogbò kò ní. Àwọn ọlọ́pàá kàn lè wọ ààyè ìdákọ́ńkọ́ tí wọ́n bá ní ìfọwọ́sowọ́pọ̀ rẹ tàbí kí wọ́n fi ìwé àṣẹ ìdájọ́ hàn ọ́ (tí adájọ́ buwọ́lù).

**Àwọn àgbègbè Ààbò**

- Ní Oṣù Kinní Ọdún 2025, ìjọba Trump fagilé àlàkalẹ̀ ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó ń darí ICE àti CBP láti yàgò fún gbígbófinró ìṣíwọ̀lú ní "àwọn ààyè tí òfin ní ìkálọ́wọ́kò sí" tàbí "agbègbè tó wà lábẹ́ ìdáàbòbò" bíi àwọn ilé-ẹ̀kọ́, iléeṣẹ́ ìtọ́jú ìlera, àti àwọn ààyè ìjọsìn.
- Síbẹ̀síbẹ̀ pẹ̀lú ìyípadà yìí, àwọn aráàlú New York ṣì tún ní ìdáàbòbò díẹ̀ ní àwọn ààyè yìí.
- Àwọn Àṣẹ Ìgbìmọ̀ Ìjọba Ìpínlẹ̀ New York 2018 kan fòfin de àwọn agbófinró ìṣíwọ̀lú ní àwọn iléeṣẹ́ ìpínlẹ̀ New York bíi ilé-ẹ̀kọ́ tàbí ilé-ìwòsàn àyàfi tí ICE bá ní ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
- Àgbékalẹ̀ Òfin Ìdáàbòbò Ilé-ẹjọ́ Wa dáàbòbo àwọn aráàlú New York lọ́wọ́ fífi òfin mú ẹni ní ilé-ẹjọ́ ìpínlẹ̀, ìlú àti ti agbègbè láìsí ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́.
- ICE àti àwọn aṣojú òfin mìíràn ò leè wọlé sí "àwọn ààyè aládàáni" láì ní ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́ tàbí ìyọ̀nda oníwun.

**Mọ̀ nípa ìwà ìbàjẹ́ àwọn aṣíkiri.**

- Òfin àwọn aṣíkiri le. Ṣọ́ra nígbàtí o bá ń jíròrò ipò rẹ pẹ̀lú èyíkéyìí ènìyàn tàbí ìṣòwò
- Agbẹjọ́rò tàbí Aṣojú Ẹká ti Ìdájọ́ (DOJ) tí a fọwọ́sí fún ìmọ̀ràn òfin nìkan ní ó yẹ kí o bá sọ̀rọ̀ lórí ipò rẹ.
- Má ṣe gba ìrànlọ́wọ́ àwọn aṣíkiri láti ọ̀dọ̀ "notario," aṣojú ìrìn-àjò, ìgbáradì owó orí, ìgbáradì fọ́ọ̀mù, tàbí ẹlẹ́rì-òfin. Ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà, "notario" kì í ṣe agbẹjọ́rò!

**Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ẹjọ́ rẹ tàbí tí o ní àwọn ìbéèrè ìwọlé gbogbogbò, pe Ọ́fíìsì fún Ará Amẹ́ríkà tuntun (ONA) Ojú-òpó-ìyára ní 1-800-566-7636.**

# Ààbò Àgbègbè



**Gbogbo ènìyàn, láìka ipò ìwọlé tàbí ìdánimọ̀ sí, yẹ kí ó wà ní ààbò ní agbègbè wọn.**

### Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra àti Ẹ̀tanú

- Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ tí ó jẹ́ ìwúrí nípasẹ̀ ẹ̀tanú sí ẹ̀yà ènìyàn, àwọ̀, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìdílé, ọkùnrin àti obìnrin, ẹ̀sìn, ìṣe ẹ̀sìn, ọjọ́ orí, àìlera tàbí ìbálòpọ̀.
- Ìpínlẹ̀ New York ní Agbófinró Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra láti yanjú ìlọsíwájú nínú àwọn ìròyìn nípa ìdẹ́rùbà, ìnira àti ìwà ipá.
- Tí o bá rí ohun kan tàbí jẹ́ olùfaragbá ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra:
    - Sọ ọ́ fún Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn. Pe 1-888-392-3644, tẹ " HATE " sí 81336, tàbí lọ sí forms.ny.gov/s3/Hate-Crime-Tips. O lè ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov fún àlàyé síwájú síi
    - Láti ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra tí ó ń lọ lọ́wọ́ tàbí pàjáwìrì èyíkéyì, pe 911 lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Nígbà tí wọ́n bá ròyìn ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra, gbogbo àlàyé nípa ìrírí rẹ, ìdánimọ̀ rẹ, àti àwọn mìíràn ṣì wà ní ìkọ̀kọ̀.
- O lè ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra kí o sì gba àwọn iṣẹ́ láìka ipò ìwọlé rẹ sí.

### Àwọn Ohun Àmúlò Agbègbè

- Ọ́fíìsì Ìlú New York fún Ìdènà Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra ń pèsè àwọn iṣẹ́, àwọn ohun èlò, àti àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àjọ. Àwọn ohun èlò wà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè. Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/stophate.
- Ilé-iṣẹ́ fún Ẹ̀kọ́ Gbígbógun ti Ìwà Ipá ń ṣiṣẹ́ láti dènà, ṣe ìdíwọ́, àti láti wò ó sàn kúrò nínú ìwà ipá ìkóríra ní àwọn agbègbè New York. Wọ́n ní àwọn ètò ẹ̀kọ́ lórí ìdáàbòbò ara wọn, àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó wà nítòsí, àti agbára àwọn ọ̀dọ́. Pe 1-718-788-1775 tàbí ṣàbẹ̀wò sí caeny.org fún àlàyé síwájú síi.

**Sísopọ̀ pẹ̀lú Àgbègbè**

- AAPI
    - Asian Americans for Equality: 212-979-8381, aafe.org
    - Chhaya for South-Asian and Indo-Caribbean communities: 718-478-3848, chhayacdc.org
    - Korean Family Service Center: 718-460-3800, kafsc.org
    - MinKwon Center for Community Action: 718-460-5600, minkwon.org
    - National Federation of Filipino American Associations New York: 212-684-0542, naffaa.org
    - Sikh Coalition: 516-930-0302, sikhcoalition.org
- Ará Áfíríkà
    - African Communities Together: 347-746-2281, africans.us
    - African Services Committee: 212-222-3882, africanservices.org
    - Sauti Yetu Center For African Women: 718-665-2486, sautiyetu.us
- Mùsùlùmí/Lárúbáwá
    - Arab American Association of New York: 718-745-3523, arabamericanny.org
    - Council on American-Islamic Relations of New York: 646-665-7599, cair-ny.org
    - Muslim Community Network: 347-519-2755, mcnny.org
- Àìpéra
    - Center for Disability Rights: 585-546-7510, cdrnys.org
    - Disability Rights New York: 518-432-7861, drny.org
- Hispanic/Latino
    - Hispanic Federation: 866-432-9832, hispanicfederation.org
    - Latino Commission on AIDS: 212-584-9325, latinoaids.org
    - Mixteca: 718-965-4795, mixteca.org
    - TransLatinx: 646-882-2000, translatinxnetwork.org
- LGBTQ+
    - Caribbean Equality Project: 347-709-3179, caribbeanequalityproject.org
    - Gay, Lesbian, Bisexual and Transgender Community Center: 212-620-7310, gaycenter.org
    - New York City Gay and Lesbian Anti-Violence Project: 212-714-1141, avp.org
- Abínibí Amẹ́ríkà àti Abínibí Alaska
    - American Indian Community House: 646-575-3638, aich.org
    - North American Indigenous Center of New York: 516-930-0302, naicny.org

# Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS



**Ọ́fíìsì NYS fún Ará Amẹ́ríkà tuntun**

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá nílò ìrànlọ́wọ́ òfin ọ̀fẹ́, pe ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀-ìyára náà ní 1-800-566-7636. Gbogbo àlàyé ìpè jẹ́ àṣírí. Ìrànlọ́wọ́ wà ní èdè 200+.

**Ẹ̀ka Ètò Ìlera NYS**

- Béèrè fún Ìtọ́jú Ìlera: pe 1-855-355-5777 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nystateofhealth.ny.gov.

**Ọ́fíìsì NYS fún Ìlera Ọpọlọ**

- Fún àwọn ìbéèrè nípa àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ tàbí láti wá olùpèsè iṣẹ́ ìlera ọpọlọ, pe 1-800-597-8481 tàbí ṣàbẹ̀wò sí omh.ny.gov.
- Ìlà-ìpè ìyára Ìdènà Ìṣekúparaẹni Ìjọba àpapọ̀ : Tí ẹ̀mí rẹ tàbí ti ẹlòmíràn bá wà nínú ewu tó ń súnmọ́, pe 911. Tí o bá wà nínú wàhálà àti nílò ìrànlọ́wọ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, pe 1-800-273-8255 tàbí Tẹ "GOT5" sí 741-741.

**Ọ́fíìsì NYS fún Ìdènà ti Ìwà-ipá Ilé**

- Tí ìwọ tàbí ẹlòmíràn bá wà nínú ìbáṣepọ̀ tí ẹlòmíràn ń ṣàkóso nípasẹ̀ ọ̀rọ̀, ti ara, tàbí ìlòkulò ìbálòpọ̀, tàbí àwọn ọgbọ́n míràn, pe Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ NYS fún Ìwà Ipá Inú Ilé ní 1-800-942-6906.
- Láti bá agbẹjọ́rò sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ ayélujára, ṣàbẹ̀wò sí opdv.ny.gov. Ó wà ní 24/7 ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè.

**Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti NYS**

- Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti ṣe ìpinnu láti dáàbò bo àti ìgbéga ààbò àti ìlera àwọn òṣìṣẹ́, owó oṣù, àti ipò iṣẹ́.
- Fún àlàyé nípa owó oṣù àti òfin wákàtí, ìlera ibi iṣẹ́ àti ààbò, tàbí láti fi ẹ̀sùn kan, pe 1-888-469-7365 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/safety-and-health
- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú Ìdánilójú Àìríṣẹ́ṣe, pe 1-888-209-8124 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/unemployment/unemployment-insurance-assistance.

**Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn**

- Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn ní New York fòfin de ìyàtọ̀ ní àwọn agbègbè bíi ìgbanisíṣẹ́, ilé, gbèsè, ẹ̀kọ́, àti àwọn ibi ìgbé gbogbogbò, tí ó dá lórí ọjọ́ orí, ẹ̀yà, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìbálòpọ̀, ìbálòpọ̀, ìdánimọ̀ ọkùnrin àti obìnrin tàbí ìfihàn, ipò ìgbéyàwó, àìlera, ipò ológun, àti àwọn ẹ̀ka mìíràn.
- Tí o bá rò pé wọ́n ti yà ọ́ sọ́tọ̀, fi ẹ̀sùn sílẹ̀ ní 1-888-392-3644 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov.

**Ètò-Ilé NYS**

- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú wíwá ilé tí kò wọ́n, pe 1-877-428-8844 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nyhousingsearch.gov.
- Fún àlàyé lórí tẹ́tẹ́ ilé tí kò wọ́n ní ìlú New York, pe 212-863-7990 tàbí ṣàbẹ̀wò sí housingconnect.nyc.gov.
- Fún àlàyé lórí ẹ̀tọ́ àwọn ayálégbé ní Ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí ag.ny.gov/publications/residential-tenants-rights-guide.

**Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá**

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá ti ní ìrírí ìwà ìkóríra, Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá lè ní ànfàní láti ṣe ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú owó ìtọ́jú ìṣègùn àti ìnáwó ìmọ̀ràn, ìsìnkú àti iye owó ìsìnkú, owó oṣù tí ó sọnù, àti àwọn irúfẹ́ ìrànlọ́wọ́ mìíràn.
- Pe 1-800-247-8035 tàbí ṣàbẹ̀wò sí ovs.ny.gov fún àlàyé síwájú síi.

Láti wo ìwé yìí lórí ẹ̀rọ ayélujára tàbí ní àwọn èdè míràn, ṣàbẹ̀wò sí nyic.org/KYR tàbí ya àwòrán kóòdù yìí:

Tí o bá ní àwọn ìbéèrè tàbí àwọn àsọyé nípa irinṣẹ́ yìí tàbí àlàyé nínú rẹ, jọ̀wọ́ kan si:
Bryan Lee – blee@nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York (NYIC) jẹ́ ìlànà àpapọ̀ àti àjọ alátìlẹ́yìn tí ó ń ṣojú fún àwọn ẹgbẹ́ aṣíkiri àti àwọn ẹgbẹ́ ẹ̀tọ́ àwọn aṣíkiri àti àwọn asásálà tó lé ní 200 káàkiri New York.

A fojú inú wo ìpínlẹ̀ New York tí ó lágbára nítorí pé gbogbo ènìyàn ni wọ́n gbà, tí wọ́n ń tọ́jú wọn dáadáa, tí wọ́n sì fún wọn ní àǹfàní láti lépa àlá wọn. Iṣẹ́ wa ni láti so àwọn aṣíkiri, àwọn ọmọ ẹgbẹ́, àti àwọn alájọṣepọ̀ pọ̀ kí gbogbo àwọn ará New York lè gbilẹ̀.

**New York Immigration Coalition**
131 W 33rd St, Ste 610
New York, NY 10001
212 627 2227
nyic.org